IBADAN UNIVERSITY LIBRARY
16 SEP 1974
EDITOR IMOLE OWURO
14/9/74
IBADAN.

Kongi Nap
7, 19, 24
ASIKO Bks
10 18, 40, 41
ROSS BKS
23& 13

# Imọlẹ Owuro

UNITY NPS
For 3 sure drawr in Wk 7 try to see The Manager Unity Pools House, E4/226, Gbelekalẹ Ibadan.
See him with ₦5 before 2 p. m. on Saturday.
1, 7, 13, 19

Ẹsin Ọrọ Wa: "IMỌLẸ DE! OKUNKUN PARADA"
Independent Paper VOL. XIII No 656 SATURDAY SEPTEMBER 14 – FRIDAY SEPTEMBER 20, 1974 5K. (KỌBỌ MARUN

# ỌMỌ IYA MẸTA LU ENIA PA BAMUBAMU

ILE - ẸJỌ giga ilu Ugheli ni Ipinlẹ Ado - Ibinni ti dajọ iku fun awọn enia mefa ninu eni ti ọmọ iya mẹta kan wa fun jijẹbi ẹsun pe nwọn lu ọkunrin kan pa bamubamu, nwọn si sinku rẹ ni bonkẹlẹ.

Awọn ọmọ iya mẹta na ni Nakorere Ginibo, Sunday Ginibo ati Abudu Owho Ginibo. Awọn mẹta miran pẹlu wọn ni Ọsa Kwakpowe, Glory Walka Oghenede, ati Okpoarere Deke ti gbogbo wọn l'apapọ ngbe Ekakpamre ni iha Ila - oorun ilẹ awọn Iṣọbo.

Awọn afẹsunkanni fi ẹsun kan awọn enia na pe, nwọn gbimọpọ pa ọkunrin ara abule na kan Omagbemi Ọgangan ni ọjọ kẹfa oṣu keji ọdun ti o kọja l'abẹ awawi pe ọkunrin na jẹ oṣo, ati pe oun ni o pa ọmọ ọkan ninu awọn ọdaran na jẹ.

Ẹni keje ti awọn afẹsunkanni pe l'ẹjọ pẹlu wọn ṣugbọn ti o moribọ ninu ẹjọ na ni Karo Okotete ti nwọn pe ni Babalawo ti o woṣẹ fun wọn pe oṣo ni ọkunrin oloogbe na iṣe.

Nigbati wọn nrojọ na lọ, ile ẹjọ gbọ bi o ṣe jẹ pe nigbati ọkan ninu ọmọ awọn enia mẹfa tihin ku, nwọn ro ni ọkan wọn pe iku aiye ni ọmọ na ku, nwọn pinnu lati tọ Babalawo lọ lati wadi

(Woju Ewe Kẹfa)

# SOHUN FI IPILE AAFIN LELE



ỌBA ỌLADUNNI AJAGUNGBADE KẸTA

NKAN bi ẹgbẹrun mọkanlelogun Naira (₦21,000) ni nwọn ri kojọ lẹsẹkẹsẹ nibi ayẹyẹ ifi ipilẹ aafin sọlẹ ati ikowojọ fun atunkọ aafin Ṣọhun ilu Ogbomọṣọ ti o waiye ni Gbọngan ilu na l'opin ọsẹ to kọja.

Ẹgbẹrun l'ọna aadọjọ Naira (₦150,000) ni a lero pe yio pari iṣẹ na. Nkan bi ẹgbẹrun lọna ọgbọn ni nwọn kọ ri kojọ nigba ifilọlẹ eto na ati pe ₦2,047 ni nwọn ri kojọ nibi ifilọlẹ ti Ogbomọṣọ Parapọ ẹka ilẹ ṣe ni 27/7/74 ọdun yi fun eto kanna.

Ara awọn nkan alarinrin ti o ṣe pataki nibi eto topin ọsẹ to kọja yi ni iwe kan ti Ọgagun agba awọn ọmọ ogun oju omi Orilẹede wa yi Commander Akinwale Wey kọ pe gẹgẹbi ọkan ninu awọn ọmọ Ogbomọṣọ inu oun dun fun eto na

(Woju Ewe Kẹfa)


## Kini o dun to yi?

ILẸ—IṢẸ OGO OLUWA KIITAN TRADING STORES, ti gbe awo rẹkọọdu nla titun ti gbajumọ oṣere nni FATAYI OLOWONYỌ ati awọn oṣere rẹ ṣẹṣẹ ṣe jade, eyiti nọmba rẹ jẹ OKLP 17, VOL. 3.



FATAYI OLOWONYỌ
(Onijita Aramọnda)

Awo na pabambari, o le gongo. A gbọ ma le lọ ni orin inu awo titun na. Ti ilu ti nwọn lu ninu rẹ ni ki a sọ ni tabi Jita aramọnda ti Olowonyọ ta sinu rẹ ? "Ko dun l'odo" ni awo rẹkọodu yi, "ti o ba dele a di oyinmọmọ'

Bakanna ni awo rẹkọodu OKLP 11 ati OKLP 13, VOL. 1-2, ti ẹ ti mbeere rẹ ti wa bayi fun tita.

Kọṣeemani ni awọn awo wọnyi fun igbadun abẹle nigbagbogbo.

Ẹ le ri wọn ra ni ile - itaja rẹkọọdu l'adugbo nyin tabi l'ọdọ Olupinja:

OGO - OLUWA KIITAN
TRADING STORES
51, Railway Line
Odi - Olowo, Muṣin
Tel. 46252
Tabi ni Ẹka wọnyi:
*119, Herbert Macaulay St, Ebute - Mẹtta.
*2, Badejọ Street, Agege Lagos State.

AKEDE ỌNA IYE

# Se itore-aanu re si ibi ti o to

"Ẹ kiyesi ara ki ẹ ma ṣe itọrẹ aanu nyin niwaju enia, ki a ba le ri nyin: bi o ba ri bẹẹ, ẹnyin ko li ere lọdọ baba nyin ti mbẹ l'ọrun.

Nitorina nigbati iwọ ba nṣe itọrẹ aanu rẹ, maṣe fun fere niwaju rẹ, bi awọn agabagebe ti nṣe ni sinagọgu ati ni ita, ki nwọn ki o le gba iyin enia. Lootọ ni mo wi fun nyin, nwọn ti gba ere wọn na" Mattew 6, 1-2.

LATI ỌWỌ WOLI S. I. OWOẸYẸ

Lai ṣe aniani, iwa igberaga ati ṣekarimi ti gba ile aiye kan l'ode oni. Ati ọmọde ati agba, ati okunrin, ati obinrin ni nwọn ti sọ igberaga di aṣa wọn.

Ṣugbọn ki l'o nfa iru iwa bayi? Ohun ti o nfa a ni aini ẹkọ nipa ọrọ Ọlọrun. Nigbati enia ko ba ni ẹkọ ọrọ Ọlọrun, oluwarẹ yio maa gberaga bẹẹni Ọlọrun si kọ oju ati ọkan igberaga.

Ẹni ti o ni ọkan igberaga a maa jọ araa rẹ l'oju nigbagbogbo; a maa ka araa rẹ si ẹni ti o ju gbogbo enia lọ ni gbogbo ọna, eyi a si maa han ninu iwa ati iṣe rẹ.

Bi onigberaga ba nṣe ohunkohun, tigberagatigberaga ni' Kaka ki onigberaga maa fi oore Oluwa han ninu iwa ati iṣe rẹ, nṣe ni yio maa fi igberaga ṣe e. Kaka ki o nawo rẹ fun a ti dupẹ lọwọ Ọlọrun, anadanu ni yio maa na an ki o le gba iyin l'ọdọ ọmọ enia.

Melo ni a o ka ninu ọmọ enia l'oni ti o nnawo wọn si ọna ti ko l'ere? Melo ni o nnawo tirẹ si ọna iparun?

Ọpọ owo ti ọmọ aiye yi nna ni o njasi anadanu, ṣugbọn ẹni ti o ba na owo tirẹ fun Oluwa ki yio jasi anadanu bi o ti wu ki o ri.

Bi enia ba lowo ti o fi owo rẹ ra kẹkẹ ologeere, kẹkẹ na le bajẹ. Bi o fi owo na ra Mọtọ, mọtọ le parun, ki yio si akọle rere kan fun iru enia bẹẹ ninu aiye. Ati pe, iru ipo yowu ki enia le fi owo ra ninu aiye ẹni na yio fi ipo na silẹ ni ọjọ kan, ẹlomiran yio si bọsi ipo na.

Ṣugbọn ipo kan wa titi aiyeraiye ti a kii gba lọwọ enia. Ipo yi ni ipo ti o fi ile Ọlọrun ṣe igbẹkẹle rẹ.

Lakoko ti Solomoni fi ile Ọlọrun ṣe igbẹkẹle rẹ; ninu ọpọ ile ti o ni o kọ ile fun Ọlọrun. Apẹrẹ igbẹkẹle Ọlọrun ti Solomoni ṣe lakoko na ni ẹgbẹẹgbẹrun enia nka ninu Bibeli Mimọ ninu Awọn Ọba Kini Ori 6, 1—38 titi di oni yi.

Ọpọ olowo ti o ju ti Solomoni l'o wa ni Israeli ati Egypti nigbana, ṣugbọn sibẹ, eṣu fọ ọpọ l'oju ẹmi, nwọn si nna owo si ibi ti ki iṣe ọna gẹgẹ bi ọpọ alagbara wa akoko yi ṣe maa nnawo fun faaji ṣekarimi ti asan aiye yi.

Lẹhin ti Ọlọrun ba ti gbe wọn dide lati idile talika ti o si sọ wọn di enia nla, Onilu a maa lu, a si maa korin ki wọn pe, Olowo ni iran wọn. Nigbanna inu wọn a dun, nwọn a si maa fi araa wọn han bẹẹ gẹgẹ.

Iru awọn enia wọnyi nna owo wọn si ibi adanu, nibiti ko ni ere kan. Nwọn a kun fun igberaga, nwọn a si ma nawo wọn si ibi ti ọmọ araiye yio ti maa kan saara si wọn; ni ọdọ enia na ni ere wọn pin si.

Iru iwa kanna yi a maa lo wọn nigbati nwọn ba nṣe itọrẹ-aanu nitoripe pẹlu oju ati ọkan igberaga ni.

Ṣugbọn itọrẹ-aanu yi jẹ dandan fun iwọ ati emi-yala olowo ni tabi alaini. Talaka ti o ṣe itọrẹ-aanu l'ọna ẹtọ niwaju Jesu Kristi nijọsi gba ogo ti o gaju lọ laarin ogunlọgọ enia ti o wa sibẹ bi nwọn tilẹ jẹ ọlọrọ.

Nitorina, ọrọ Ọlọrun nkilọ fun ọ l'oni yi lati maa na owo rẹ si ọna ẹsin Ọlọrun nibiti o ni ere julọ paapaa ere aiye ati ti ọrun.

Ọrọ yi ki iṣe t'emi tabi tirẹ nikan bikoṣe ti gbogbo wa lapapọ. Ẹ maa fi ohun ini nyin bọwọ fun Oluwa, ẹ si maa nawo nyin fun igbeleke Ọrọ Rẹ pẹlu nitoripe ninu gbogbo owo ti Solomọni Ọba na ninu aiye rẹ, eyi ti o fi kọ ile Oluwa nikan ni yio maa fun un ni orukọ rere titi aiye.

Ninu gbogbo owo ti obinrin talaka opo kan na ninu aiye rẹ, owo idẹ wẹwẹ meji pere ti o na pẹlu inu kan ati ọkan kan ninu ile Oluwa l'o fun un ni orukọ rere titi di oni yi.

Nitorina iwọ ọmọ enia ti o ngba oore ile Oluwa ti o si nna owo rẹ fun eṣu, ohun ti a le fi ọrọ rẹ we ni ẹlẹdẹ ti nwọn nwẹ ara rẹ ti o tun npada sinu ẹrọfọ.

Ọpọ l'o maa ntori aniyan ọjọ ọla ti kii ranti ile Ọlọrun lati ṣoore sibẹ, nwọn a si bẹrẹ sii ta tẹtẹ tabi ki nwọn maa fi owo ṣe ogungun agbara kiri.

Lẹhinna ti owo yi ba ja si ofo nwọn a waa sọ pe awọn fun Oluwa. Isọkusọ gbaa ni iru ọrọ bẹẹ jẹ nitoripe nwọn ko fi owo wọn fun Oluwa rara, oogun (eṣu) ni nwọn fi fun.

Nitorina iwọ ọmọ enia, maa fi ohun ini rẹ yin Oluwa. Nigbati o ba si nṣe itọrẹ-aanu rẹ, maa ṣe e si ọna ti o tọ, iwọ yio si ri ọpọlọpọ ere gba pada lọwọ Oluwa. Ma ṣe na owo rẹ fun ohun asan aiye yi ki iwọ ki o ma baa jere asan.

Ọlọrun paapaa si npe ọ pe: "Ẹ tete kọ wa Ijọba Ọlọrun ati ododo rẹ, gbogbo awọn ohun rere ti o ku ti o mbere ni a o si fi kun un fun nyin" Matteu 8,33.

ADURA

Oluwa, fa mi si ọna otitọ Rẹ, Amin.



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwasu na.

## Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

10,995 Kamọru Ajifẹrukẹ, Ibadan
10,996 Taiwo Akinsanmi, Abẹokuta
10,997 Ọmọlara Akinsanmi, Abẹokuta
10,998 Ọlawale Akinsanmi, Abẹokuta
10,999 Bọla Babalọla, Ibadan
11,000 Akinkunmi Ayọade, Ogbomọṣọ
11,001 Caleb Ọla, Ile-Ifẹ
11,002 Thompson Bamisaiye, Iragbiji

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA
DI

**Omo Egbe Imole Owuro**

(Iwe idi ọmọ Ẹgbẹ)

Orukọ rẹ ______________________

Adirẹsi rẹ: ______________________

Ọmọ ilu ti o jẹ ______________________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akọwe Ẹgbẹ)
P. M. B. 5230, Ibadan

## IWE ORO OLORUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkọọkan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kobo (50k) pere.

Awon Iwe na ni:

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JỌWỌ ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa. Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ,
Box 1206,
Ibadan.

# KI LO SELE?

## Omo kewu se wolimo

IROHIN lati ilu Kaduna fi ye wa pe Ijọ Ansaru-Deen ṣe wolimọ t'o larinrin fun awọn ọmọ kewu wọn mẹsan ti nwọn ke Alukurani pari. Ninu Mọṣalaṣi wọn ti o wa ni opopo Abẹokuta, Kaduna ni nwọn ti ṣeto na ni ọjọ kejidinlogun oṣu kejọ ẹdun yi.

Ẹni ti o ṣe Alaga eto ọjọ na ni Alhaji Onigbanjo, Alhaja Adijat Jinadu si ni Alaga obinrin. Imam fun Ijọ Nurudeen na ni Alhaji M.A. Olokodana, olori olukọ wọn ni Ismail T. Ọlọrungbẹbẹ. Awọn olukọ yoku ni Husaefatu Nafiu, Yusufu Salawudeen Bamigboye; Manager M.A. Lawal, awọn aṣoju yoku ni A. R. Gbọnjubọla, Alhaji B.A. Yusufu.

Awọn ọmọ mẹsan ti nwọn ṣe wolimọ Kurani na ni Buniyaminu Belo, Sikiru Ayinde, Jimọ Raimi, Yusau Oginni, Baṣiru Raimi, Ṣẹrifatu Belo, Amudatu Ọmọtayọ, Musilimọtu Sanni ati Kudiratu Akande.

Ara awọn enia ti o wa sibẹ ni Alhaji Arẹẹgbẹ Alhaji Akande A. T.S. Alhaji B.O. Ogunsanya, G.S. Alhaji Karimu, Jimọh Ade Belo, Alhaji Raimi, Alhaja Aṣiawu Balogun, Aminatu Kadiri, Ṣifaawu Raimi, Rafatu Raimi, Alhaja Wulẹmọtu, Alhaja Abibatu, Musilimọtu Ọmọtayọ.

## Alhaji Mukadmu komo

IROHIN ti o tẹ wa lọwọ lati ilu Ondo fi ye wa pe Alhaji Mukadamu M. A. Imam ti o ngbe ni Opopo Odotu nilu Ondo ṣe ikọmọjade ọmọbinrin kan ti Ọlọrun fi ta oun ati iyawo rẹ Iyaafin Kudiratu Imam l'ọrẹ laipẹ yi.

Orukọ ti nwọn sọ ọmọ na ni Latifatu Alakẹ Imam. Awọn ti o ṣeto isọmọlorukọ na gẹgẹ bi ilana ẹsin Islam ni Alhaji Tafusiri ti Ondo ati Alhaji Asisi Akinlẹwa Iwo.

Ọpọ enia ni a gbọ pe o wa sibi inawo na, awọn obi ọmọ si fi jijẹ tẹ wọn l'ọrun


### Educational

OTUTU Co—Educational Grammer School, ML5 Ifẹ Road, Ibadan c/o N4/496 Yẹmẹtu—Aladọrin Road, Ibadan.

Vacancies exist in Classes I to V Apply with self addressed Stamped envelope enclosing 50k for forms.

——Principal





AWORAN ẹgbẹ yi nṣe afihan ara awọn enia ti awọn ọmọ ogun oju omi fun ilẹ Gẹẹsi fa yọ kuro ninu ihamọ ogun ni ilẹ Cyprus nibiti ogun gbigbona giri-giri ti ṣẹlẹ laarin ọmọ ogun ilẹ Greece ti o wa ni ilẹ Cypruṣ ati ọmọ oguu ilẹ Turkey lori ọrọ akoso ilẹ Cyprus.

Awọn enia mẹta na ti nwọn kun fun ayọ lẹhin akoyọ wọn ni lati apa osi Stephen, Katie, ati James Catteril

## Adekeye di Ọloro—ruwo

NI aipẹ yi ni nwọn jawe oyẹ le ọkunrin Agbẹ eni aadọta odun kan Ọmọ Ọba Lawani Adekẹyẹ lori gẹgẹ bi Ọlọrọruwọ ilu Ọrọruwọ lẹba Ikirun.

Oloye titun na, ẹni ti o wa lati idile oyẹ Ṣangoyọyin ni o gba ipo Ọlọrọruwọ ana Oloye Noah Adedọja ti o fi'lẹ bora bi aṣọ ninu ọdun 1971.

Lẹhin ti o ti gori itẹ tan, Oloye na dupẹ lọwọ Ijọba Iwọ-Oorun, awọn Afọbajẹ ati enia ilu Ọrọruwọ fun atilẹhin wọn, o si ṣe ileri pe oun yio lo ipo oun ni rere fun ilọsiwaju ilu Ọrọruwọ.

29

31

38


IWE IGBAẸLODE DARA PUPỌ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 10k
2. Kuraui esu marun Yoruba 55k Esu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (15k)
4. Zabura ati itumọ (55k)
5. Zabura Yoruba (40k)
6. Iwe Aiye Akamara (50k)
7. Iwe Eniaṣoto (50k) Adedẹwẹ (35k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni nla (₦1.50)
10. Kekere (30k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦1.5) Kekere (45k)
12. Itan Anabi ati Yisa (55k)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FIOWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeoyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi-Iṣin St, Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin.



ARA NFAAJO

MAGNATONE BLOOD TONIC




MAGNATONE jẹ TỌNIKI atata-a tun ẹjẹ ṣe fun ọmọde ati agbalagba.

Beere ni ile itaja oogun ti o wa ni adugbo rẹ tabi ni:

BASOTO PHARMACY
63, IDUMAGBO AVENUE
ITA AGARAWU,
LAGOS.

# Awon Ọde Oyo kilo fun Ọlọsa

AWỌN Ọdẹ Aṣọde ilu Ọyọ ti kilọ fun awọn Igara Ọlọṣa ti o ba wa ni aarin ilu ọyọ ati agbegbe rẹ pe ki nwọn tete yẹra kuro nilu Ọyọ bi bẹẹ kọ, agbako yio de ba wọn.

Ninu ipade pataki kan ti awọn Ọmọ ẹgbẹ Ọdẹ Aṣọde na ṣe ninu ile ipade wọn ni adugbo Ọpapa nilu Ọyọ, nwọn sọ pe asiko to wayi lati Jagun pẹlu awọn Igara Ọlọṣa ti o wa laarin ilu Ọyọ ati agbegbe rẹ.

Ọgbẹni Ajibade Aderintọ ti iṣẹ Olori ẹgbẹ na kesi awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ pe ki onikaluku wọn lọọ mura gidigidi nitoripe awọn gbọdọ gbogun ti awọn Igara Ọlọṣa na ni ati pe agbako nla ni ogun na gbọdọ jẹ lori awọn Ọlọṣa ti nyọ ilu Ọyọ lẹnu.

Olori Ọdẹ Aṣọde na fi kun un pe irohin ti o njade nipa ọṣẹ ti aw.n Igara Ọlọṣa wọnyi nṣe kiri kọ oun lominu pupọ, o si yẹ ki awọn jagun pẹlu wọn eyiti oun mọ daju pe ajaṣegun ni oẓun na yio yẹ

Ọgbẹn Ajibade tọkasi iku Ọdẹ Aṣọde meji. kan ti o ṣẹlẹ laipẹ yi ati awọn iṣẹlẹ miran ti o ti nwaiye nipa iwa ijamba ti awọn ole ati Isọra Ọlọpa na nhu kaakiri aarin ilu Ọyọ.

Bakanna ẹwẹ, ni o tun kilọ fun awọn ọmọ ilu Ọyọ pe iṣe ọdẹ aṣọde ki iṣe isẹ ajalu, nitoripe awọn ti o nṣiṣẹ na jẹ ọdẹ hauhau tẹlẹ, ati pe ẹnikẹni ti o ba fẹ maa ṣe iṣẹ nilati ri i pe oun da ara oun l'oju gidigidi lati le pitu ti ọdẹ npa pẹlu awọn Igara Ọlọṣa wọnyi.

Ki ipade na too pari ẹgbẹ na pinnu lati siṣẹ na gidigidi fun alafia ati ifọkanbalẹ awọn enia ilu Ọyọ ati lati fọwọsowopo pẹlu Ọba Lamidi Adeyemi Kẹta, Alaafin Ilu Ọyọ.

Diẹ ninu awọn ọdẹ ti o wa sibi ipade na ni Ọgbẹni Okunade, Ojẹ Agbako, Adeyanju Amọọ, Ajayi ile Dopẹmu, Salami Adelẹke, Busari Atoyesi, Andrew Ọladẹjo Ogunlade, Wahabi Mustafa ati Lasisi Ọjoawo.



AJIBADE ADERINTỌ
Olori Ọdẹ Aṣọde Ọyọ

# Pools Pools

## Nap: 23, 35, 49

**Ojo Adisa**
(11&7) 7, 8, 9, 10, 11?
OJO ADISA,
N4/273 Adeọyọ Oje Rd. Ibadan.

# Ọmo iya meta lu Enia pa

(Lati oju ewe kini)

ọrọ na.

Nigbana ni nwọn ranṣẹ si Babalawo kan ti o wa ni toṣi abule na pe ki o wa. Babalawo na ni o sọ fun wọn pe Ọmagbemi Ogangan jẹ oṣo ati pe oun ni o pa ọmọkunrin na.

Irohin sọ pe nigbana ni awọn enia mẹfa na lọ sile Omagbemi Ogangan, nwọn si bẹrẹ si i lu u bi ẹni maa ku,

Nigbati nwọn lu u tan, nwọn fi okun de e nwọn si tilẹkun mọ ọn.

Awọn afẹsunkanni sọ pe, bayi ni awọn ọdaran na ṣe pa Omagbemi Ogangan ti nwọn si lọọ sinku rẹ sinu igbo kan leti odo ni bonkẹlẹ

Siwaju si i, awọn afẹsunkanni sọ pe lẹhin ọsẹ bi i melo kan ni awọn ọtẹlẹmuyẹ too r'idi ọrọ na ti nwọn si hu oku ọkunrin na wa sile iwosan fun ayẹwo,

Awọn enia mẹtala ni o jẹri gbe Ọba ni akoko ẹjọ na ninu ẹni ti Dokita ti o yẹ oku ologbe na wo wa. Babalawo sẹ pe oun ko mu ologbe na ni oṣo.

IDAJỌ

Ninu idajọ rẹ Adajọ ile ẹjọ na Ọlọla Ovie-Whiskey sọ pe oun gba ẹri ti awọn agbefọba jẹ gbọ, oun ko si ni iyemeji pe nṣe ni awọn enia mẹfa na finufindọ pa oloogbe Omagbẹmi lati gbẹsan iku ọmọ Abudu Ginibo ti nwọn gbagbọ pe ologbe na ni o pa a jẹ.

Nigbana ni Adajọ na da wọn lẹbi iku, o si tu Babalawo wọn silẹ pe ki o maa lọ ni alafia nitoripe ko si ẹri to lati da a lẹbi.

# Aaafin Sohun

(Lati oju ewe kini)

nitoripe Baba oun agba, Alagba Akinwale Ojo ọmọ ilu Ogbomọṣọ ni.

Ọgagun Akinwale Wey se ọpọlọpọ awọn alaye sinu iwe rẹ, o si fi ọgọrun Naira (₦100) ranṣẹ fun eto atunkọ aafin Ṣọhun Ọba nwọn.

Nkan alarinrin miran tun ni Oye Gbọbaniyi ilu Ogbomọṣọ ti Ṣọhun Ọba Ọladunni Oyewumi Ajagungbade III fi gbajumọ onisowo ọmọ Ogbomọṣọ kan to wa l'Eko, Alhaji Muritala Adams jẹ.

Oloye Muritala Adams ẹniti o kọ ti da ẹgbẹrun marun Naira tẹlẹ tun da ẹẹdẹgbẹta Naira (₦500) nibi ayẹyẹ ti a wi yi.

Oloye Victor Lajide ti o ṣe Alaga ọjọ na pẹlu da ẹgbẹrun marun ole igba Naira (₦5,200).

Nigbati on sọrọ l'ọjọ na, Ṣọhun Ogbomọṣọ, Alaiyeluwa Ọba Ajagungbade dupẹ gidigidi lọwọ awọn enia Ogbomọṣọ fun ifẹ inu ati ọkan ti wọn fi iṣe idawo na.

Ọba Ajagungbade ran awọn enia leti pe ilọsiwaju ati igbega ılu na di ọwọ wọn. O ṣe afikun pe ki nwọn ma ṣe aarẹ ọkan nipa akitiyan wọn lati wa alafia awọn enia ilu ati gbogbo ogo ti o yẹ fun apọnle ati idagba soke ilu na lọnakọna

Alaiyeluwa na ṣe akiyesi pe awọn ọba alaiye jẹ baba ati alagbọrandun fun awọn enia wọn. O ni gẹgẹ bi baba, nwọn ni lati sa fun iwa ojuṣaju ati ẹgbẹ ki awọn enia wọn le ni ifẹ ailabuku si wọn.

**Jovial Nap**
NAP 1, 13, 22
Perm 1, 5, 7, 9, 27
Pairs:- (30&31) (3&11) (24&20)
If no 7 draws come for 3 sure draws.
M.O. Oketọna
15 Oke Ọla St
APOMU

**Kani Suru Naps**
Briget Pairs. 1 and 5
4 and 6
15 and 14
Perm & Nap:- 4. 1. 15. 37. 41.

**22**
**18**

Pinted and Published by The Peoples StarPress Ltd, N4/496B Yemetu Aladọrin P. M.B. 5230 Ibadan Olotu (Editor) Lawuyi Ogunnira